# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,599 FRIDAY DECEMBER 31, 1965 (2D)

## Enia Mejila Fi Ẹgbẹ Dẹmo Silẹ

MUSHIN:- Orisirisi iwe ifi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ni a nri gba lati ibẹrẹ ọsẹ yi lọwọ awọn enia nlanla Oloye ati opomulero ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ pẹ awọn kọṣẹ ẹgbẹ Dẹmọ mọ ina esisi ki jo lẹmeji awọn ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ ti awọn ẹlomiran si dana sun asia ati awọn iwe ti o je mọ ti ẹgbẹ Dẹmọ ti o wa lọwọ wọn.

Ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti o kọ iwe si wa pe awọn kọṣẹ ẹgbẹ na mọ ni igbakeji adajọ Ijọba Ibilẹ Mushin onipo kẹta wa awọn na ni Oloye J. T. Adebinpe igbakeji adajọ ile ẹjọ Ijọba Ibilẹ Mushin ati Ọgbẹni M. S. Hassan igbakeji adajọ ile ẹjọ Ijọba Ibile Mushin onipo keji.

Ati awọn Ọgbẹni Buraimọ Ọlapade J A Bọlade, S A Adelẹji Ojo, S A Jaiyeọla Alhaji Saka Muse Ajamogun ni Iketo Ewu, Oloye F O Okuntọla alaga ile ẹjọ Ijọba Ibilẹ Mushin Onipo kẹta ninu ọrọ Oloye Okuntọla ni o ti sọ pe Ọto ni nkan ti on ro ki on to wọ ẹgbẹ Dẹmọ ṣugbọn ohunti on ba nibẹ ko ba iwa ti ẹmọluwabi enia mu rara o ni kini ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ṣe fun on tan nwọn fi on ṣe asoju agbegbe Mushin ni nu ile Igbimọ Asofin ti Ipinlẹ Iwọ Orun fun ọdun pipẹ.

Bẹna ni Oloye Olajẹkun Asani ẹniti adape re njọ "Ekute ile" na kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ pelu Ọgbẹni Michael Jimba ati Alhaji A K Adelabu ẹniti o ti fi igbakan ri je alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilu Mushin.

Gbogbo won ni awọn koṣe ẹgbẹ Dẹmọ mọ laiye ati bi awọn ba de ọrun pọlu awọn pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre awon yio maa wa ire ẹgbẹ na.

ADENIRAN OGUNSANYA SỌ PE :

# YORUBA KO FẸ AKINTỌLA

EKO:- A gbọ yanu ni Irohin ti o kan gbogbo enia yika Ipinlẹ Iwọ Orun ati Eko ni arin ọsẹ yi nigbati awọn gbele ibuso ti nwọn gbọ Irohin Oloye Adeniran Ogunsanya, Minista Alamojuto eto ile ati Ilewiwọn fun Apapọ Ijọba Naijiria sọ wi pe ohunti o fi gbogbo rogbodiyan ti o wa ni Iwọ Orun nisisiyi ni wipe gbogbo awọn ọmọ Ile Yoruba patapata ni ko ni ifẹ wipe ki Oloye Samuel Ladoke Akintọla, Alakoso Ijọba Iwọ Orun wa ni aye ti o wa ni oni yi.

Ọrọ yi ni Oloye Adeniran Ogunsanya nsọ fun Oniwe Irohin wa Ejongboro ninu ile rẹ nigbati Ejongboro lọ si inu ile Oloye na ni arin ọsẹ yi

Oloye Ogunsanya tun so siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, gbogbo ọrọ ti oloye Akintọla so ninu ẹrọ asọrọmagbesi ati ninu awọn Iwe Irohin fun ọdun Keresimesi ti o kọja lọ yi, ki iṣe otitọ rara, ọrọ na si tun jinna si ododo.

Oloye Adeniran Ogunsanya so ninu ọrọ rẹ wipe, Oloye Akintọla sọ fun gbogbo awọn enia ninu ọrọ ikini ku ọdun wipe' on fẹran awọn ọmọ Yoruba ati ile Yoruba pelu ni gbogbo awọn nkan ti on nṣe.

Oloye Adeniran Ogunsanya sọ wipe ki iṣe wipe Oloye Akintọla fẹran Yoruba ni o se nṣe awọn ohunti o nṣe ṣugbọn dipo ki o se ohunti awọn ọmọ Yoruba ba fẹ ohunti awọn ko fẹ ni o nṣe.

O tun se alaye ninu ọrọ rẹ wipe bi o ba jẹ wipe Oloye Akintọla ba fẹran awọn ọmọ Yoruba ati ile Yoruba ni Oloye Akintọla ki ba ti kuro lori aga ijoko Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ọjọ ti awọn ti dito tan ni Iwọ Orun

Bi o ba se wipe, Oloye

WO OJU EWE KẸFA

## OMI DI GOOLU NI MUSHIN

MUSHIN: Lati ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kejidinlogbọn oṣu kejila ọdun yi ni awọn enia ti nwọn kọ egbẹ wa (£2,000) ti di alairi omi mu taọi lati fi we lori ọda omi ti di awọn ... to ... ni ilu Mushin titi di asiko ti a fi nkọ iwe yi eyiti awọn enia ilu Mushin fi nlọ si ọna jijin ki nwọn to lẹ̀jri omi ni ... lati mu taoi lọ si ọna miran



Irohin fi ye wa pe ohunti o fa ti awọn enia ilu Mashin ati apakan ni Idioro ko fi ri omi mu ni moto Bọọsi ti iṣe ti Ijọba ibilẹ ilu Eko (L. M. T. S.) ti o lọ jabọ sinu gọta nla kan ni opopo ọna Agege motor Road, Mushin eyiti o jẹ wipe moto Boosi na si ba ẹrọ omi kan eyiti o jẹ pe ẹrọ omi na lo nfun awọn enia ilu Mushin ni omi ti nwọn ngmu jẹ ti ko si ọna miran ti omi le ṣe gba de ilu Mushin.

Ọpọlọpọ awọn enia to ngbe ni ilu Mushin lo jẹ wipe nwọn yio rin ibusọ meje ki nwọn to le ri omi pọn.

Ninu awọn enia na tun fi ye oniwe irohin wa pe ọpọlọpọ ninu awọn ni yio lọ si ini iṣẹ wọn ti nwọn ko ni we ati pe ki yio si omi fun wọn lati fi we bikoṣe pe pẹlu agbara ni nwọn fi ri omi mu

Oniwe irohin wa ran fi ye wa ninu irohin rẹ pe ọpọlọpọ awọn enia ilu Mushin ni o lọ si Odo kan ti nwọn npe ni Odo Isolọ lẹba Mushin lati lọ pọn omi ati pe gbogbo odo na lọ si kunṣọyọ fun awọn enia ti nwọn nṣe agbara lati le ri omi pọn.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe iṣẹ nla ni ọrọ omi ti ko si ni ilu Mushin ni jẹ fun Ọgbẹni Nathaniel Bankọle ti o ngbe ilupeju ti o nta omi fun awọn enia ati pe o si ja ohunti ga ju agbara rẹ lọ I ri awọn ọkẹsimọye awọn enia to wa si ile ogbe ni na lati wa ra omi lọwọ rẹ.

Ọgbẹni Bankọle tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe tẹlẹtẹlẹ pe kọbọ (1d) ni o nta garawa omi kan ati pe lati igbati awọn enia ti nkun ile on lọsan ati loru ni awọn na ti sọ fun on pe ki on ma ta omi na ni owo giga eyiti yio ju kọbọ ti on ti nta tele lọ.

Ọgbẹni Nathaniel Bankole tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe on ko gba ọrọ ti awọn enia na nsọ fun on bikoṣe wipe kọbọ (1d) kanna ni on yio ta rawa omi, o ni on ko fi kun owo om na rara.

Ṣugbọn awọn Ijọba ibile ilu Eko ti gbe ero nla kan lọ sibi ti Bọọsi na ti ja sinu gọta lati le gbe Bọọsi na jade ninu gọta pelu awọn osiṣẹ Ijọba Ibilẹ na.

# EGBE DEMO NGBERO LA-TI YO GOMINA IWO ORUN

IBADAN:-Lati ojo Abameta ti işe ojo kokanla oşu yi titi di isisiyi ni egbo Demo eyiti Oloye Samuel Ladoke Akintola nşe olori re ti nşe ipade lati igbati awon ti şe ipade Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinlę Iwo Orun ati Ile Igbimo Aşofin ti awon Iobaloba ni ojo oj 'Bo ti işe oj kęsan oşu yi lori ohunti o le fa ti Gomina Ipinlę na Oloye Odeleye Fadahunsi Oba Adesoji Aderęmi Oni ti ilu Ile-Ifę ati Oba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijębu-Remo fi kuna ti nwon ko wa si ipade Ile Igbimo mejeji na.

Ninu ero ti awon egbe Demo ngba bayi ni o ho-ya nwon yio yo Olola Odeleye Fadahunsi Gomina Ipinlę na, Oni ti Ile Ifę tio ti je Gomina Ipinlę na teIę ati Oba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijębu—Remo kuro lori Oye won.

Onirohin wa fi ye wa pe awon enia pataki meta na kuna lati lo si pa de ti egbe Demo ti nwon nşe akoso Ijoba Ipinlę na po ni ojo o o'Bo ti işe ojo kesan oşu yi ati pe ko si eniti o mo ohunti şelę ti awon enia na kuna lati si Igbimo mejeji ti nwon pe Ipade re ni jo na.

Ninu irohin ti a ri gbo wipe ninu ipade ti awon omo egbe Demo şe ni alę ojo Işegun ti işe ojo kerin-la oşu yi eyiti awon Igbi-mo na şe ni bonkelę ni a ti gbo pe ohunti nwon yio jiro re le lori ni ohunti nwon yio şe lori iwa ti awon oba ati Gomina ipin-lę na hu ati ona ti nwon yio gbe e gba lati pe awon enia na yara yi okan won pada nipa'bi nwon tişe ti nwon ko lo sibi ipade ti nwon şe na.

Iroh'n kan tun fi ye wa labęle pe awon egbe Demo ti ghero lati ran awon Aşa-ju kan lo si odo Oba Ade-soji Aderęmi Oni ti Ile Ifę ati Oba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijębu Remo lori ohunti o şelę ti awon oba na fi kuna lati wa si Ile Igbimo Iobaloba ti Ipin lę na ati Ile Igbimo Aşofin Ijoba Ipinlę Iwo Orun Nai-jiria eyiti awon Oba pelu awon omo egbe Demo jijo şe napo.



**Olola Odeleye Fadahunsi**
Gomina Ipinlę Iwo Orun Naijiria

Şugbon awon omo egbe Demo ko ti so ohunti nwon yio şe lori Olola Joseph Odeleye Fadahunsi ti o kuna lati wa si Ile Igbi-mo Aşofin Ijoba Ipinle na lati wa soro ti won yio fi bere ipade na gegebi Go-mina Ipinle na.

Irohin fi ye wa labęle pe awon omo egbe Demo ti ngbero kan labęle lati yo Gomina Ipinle na Olola Odeleye Fadahunsi kuro gege bi Gomina Ipinlę na.

Irohin tun fi ye wa labę-lę pe awon omo egbe Demo ko ti jiroro lori awon Oba ati Ijoye ti nwon wa sibi ipade awon lobaloba ti nwon şe ni ojo ojoBo ti ise ojo kesan oşu yi eyiti nwon yio yan gegebi mini-sita ti ko ni ise kankan fun Ijoba Ipinle Iwo Orun Naiji tia ninu awon Oba tabi Ijoye. Şugbon itohin fi pe



OBA AWOLESI
Akarigbo ti Ijebu—Remo

awon egbe Demo ti se eto nwon si ti ko or ko awon kan ti awon yio mu sile ge-gebi awon minisita ti ko ni işe kankan.

Gegebi eto ti awon egbe Demo ti şe sile lasiko ipade Ile Igbimo mejeji ti o şe ipade rapo ni pe Gomina Ipinlę na yio ba awon omo Ile Igbimo mejeji soro lati fi si ipade lori ona eto ofin

Bakanna a ewi ni Oni ti Ile-Ife Oba Adesoji Adere mi ni lati soro ninu ipade ti Ile Igbimo mejeji na ati pe oi o si ba awon Oba ati Ijoye ti o je omo Ile Igbi mo lobaloba soro ninu ya ra kan ti nwon yio ti jiroro tęlę ki eto ipade ojo na to berę.

Ninu eto ti awon egbe Demo ti şe silę nipe Oba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijebu—Remo ni yio yan eniti nwon yio fi şe alaga Ile Igbimo awon lobaloba.

Bakanna ni nwon tun fę ki Oba na soro fun awon omo Ile Igbimo lobaloba lori ohunti o ti şelę nipa eto Işelu ni Ipinlę na,



OBA ADEREMI
Oni Ifę


# KERE O !

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA" to şeşe jade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na je fun omo Yoruba Iwe na kun fun itan işedalę Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti omo re han ninu rę.

Maşe jeki nwon rohin itan ilu rę fun o

3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tirę ranşę si:

ES N KOGBOGUN SERVICE
8, Ijumagbo Avenue Lagos Nigeria
(Leti Oja Jankara)

# Iwe si Olotu Irohin Imọle

## Mo Kan Saara Si Esua

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin to kun ọgbọn ati oye lati kan sara si ọgbẹni Eyo Esua ti o ti fi igba kan wa gẹgẹbi Alaga Igbimọ eto ibo fun apapọ Ijọba nipa ipo na ti o binu fi silẹ laipe yi lori iwa madaru ti ẹgbẹ Dẹmọ fi ṣe eto ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.



Ogbẹni Eyo Esua

Mo si tun dupẹ lọwọ Ọgbẹni Esua fun iwa ọmọ ọkọ to fi han ti ko si duro owo ti Dẹmọ pin fun awọn enia lati le fi ta wọn tabi ki nwọn le ṣe jibiti eyiti Ọgbẹni Esua tu asiri ẹgbẹ na

Inu awa ọmọ ilẹ Yoruba yio dun bi awọn Alaṣẹ eto ibo ti nwọn jẹ ọmọ ilẹ Yoruba ba le tẹle ọna ti Esua gba yio dara lati maṣe tun ma da rogbodiyan silẹ mọ

Emi ni

Biola Adelaja

IJẸBU-ODE.

## Ẹ ma Jẹki Iwọ Orun Bajẹ

Olotu Jọwọ gba mi ni aye rampẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi awọn Alagba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tabi ọmọ ilẹ Yoruba lati jọwọ ki nwọn tete ba awa ọmọ Ipinlẹ na ṣe eto ti nwọn oṣe nipa ija ti nwọn fẹ pari larin ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ati ẹgbẹ UPGA nipa abayọri idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti o nda rogbodiyan silẹ bayi.

Mo ro pe laipẹ yi ni a ri ka ninu iwe Irohin-Imọlẹ pe awọn Alaga kan ti nwọn pe ara wọn ni 'Yoruba Elders Peace Committee'' eyiti Oloye Adetokunbọ Ademọla jẹ okan pata ki ninu wọn.

Eleyi yio jẹ ohunti odara bi nwọn ba le tete ṣe eyi ki itaiẹ ni Ipinlẹ Iwọ orun le lọ si opin ki won si tete pari ja to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ki eto alafia ati aje Ipinlẹ na le ma lọ gẹgẹbi ti atẹhin wa.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ fun mi ọkọ ọba ko ni sa nyin lẹsẹ ajinde yio ma jẹ fun nyin pẹlu

Emi ni

R, Olu Idris

Ibadan

# EGBOGI JẸDIJẸDI


BERE FUN EGBOGI
"CYCLEVEN"

Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ni le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara Awọn ẹlomiran lero wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun diẹ iyonu rẹ jo si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa keini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa ije Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tani ti o ba omu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba nyo ti o ba ṣe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon oynbo Jamani fere wa id rẹ ko ki o si dawo o işi mẹal yio daju wipe iwo yio bo lowo Jedi patapatarslaoaa tio de s i ekeji re ko si ninu gbogo begbogi or yi Nsiria Bere re ni:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm ChurchStreet Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ATI NI ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN



BERE FUN OJULOWO ADI_ELEGBO

"Congreve's odo Form—Ointment'



Atamataşe ni egbogi" ADI-ELEGBO" yi i fun itoju gbo gbo orişirişi "EGBO—ẸSẸ" ni kakkia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹrigbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio su mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si nu yio jeki oju re ru wa soke, yio si pọn daradara run bakaru ko si mo werewere ni ylo si san patapata Alafia de si ọ niyen : –

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si sale iwe yi ni egbe ranşe lọ ra. Bibeko awon Eleru abi onijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maşe gba ra o

Bere egoogi yini şobu awon :—ọ

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O. Box 333

# AWON ENIA KAN YIN BON SI OKUNRIN KAN

ILE—IFE:— Ni ọjọ 'Bọ ti işe ọjọ kẹtalelogun oşu yi ni awọn enia kan yinbọn si ọgbẹni C O Laseinde ti Işe Akowe n nu ile işẹ Onişowo koko ti a npe ni Messrs Lawrence Ọmọle And Sons' eyiti awọn enia na yin ibọn si ni ilu ile Ifẹ ni kutukutu owurọ ọjọ na ti o fi jẹ wipe lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti gbe Ọgbẹni Laseinde lọ si Ile Iwosan ti Ile—Ifẹ ati pe ninu ewu ni ẹmi ọgbẹni na wa bayi

Onjwe irohin wa fi ye wa ninu irohin rẹ pe Ọgbẹni Lasende fẹ lọ bẹ awọn oşişẹ ile işẹ won wo ni ilu Ile Ifẹ eyiti awọn enia na fi yin ibọn si ni adugbo kan ti nwọn npe ni Lagere Street Ile Ifẹ

Irohin na tun fi ye wa pe ni iwaju ori Ọgbẹni Lasende ni o ti fi ara gbọgbẹ ibọn ti awọn enia na yin si

Nigbati awọn Dokita ti ile iwosan ti ilu Ile Ifẹ mọ pe ẹmi Ọgbẹni Laseinde si wa ninu ewu ti ko si ayipada kankan ni nwọn tun gbe Ọgbẹni Laseinde kuro ninu ile iwosan na eyiti nwọn fi gbe lọ si ile iwosan to ga julo eyiti işe ti "University College Teaching Hospital" ni ilu Ibadan lati lọ şe itọju rẹ nibẹ,

Oniwe irohin wa ni ilu Ile Ifẹ tun fi ye wa pe moto Ọgbẹni Laseinde ti o wa ninu rẹ ki awọn enia na to yin ibon si ni irohin fi ye wa pe awon enia na si tun fi epo moto kun lara ki awọn to dana sun eyiti o jẹ wipe moto ayọkẹlẹ Ọgbẹni na si jona di eeru.

Ninu irohin ti o tun de ọwọ wa lati ilu Oshogbo ni ẹkun Ọshun ni a ti gbọ pe Ọpọlọpọ ile awọn olori ẹgbẹ Oşela to wa ni ilu Inisha l'ẹba Oshogbo ni a gbọ wipe awọn enia kan ti dana sun eyiti o jẹ wipe o si jona di eeru.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ Oşela na tun ba ọkẹaimọye ile jẹ eyiti o fi jẹ wipe awọn ile na lo bajẹ kọja lati tun şe ati ọkẹaimọye dukia tun ş'egbe ninu awọn ile na.

Ko si enia kankan ti awọn ọlọpa ti mu lori ohunti o şẹlẹ ni ilu na ati pe rogbodiyan to nşẹlẹ ni ilu na ko ti lọ si opin titi di asiko ti a fi nkọwe yi.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22—Feb 20) Maşe nawo ni ina kuna ki o ba le dara fun ọ lọjọ iwaju nigbati owo miran ba tun de

PISCES (Feb 21—Mar 20) Alafia yio de si ọ, ara rẹ yio si le giri giri, tobẹ ti iwọ yio nitẹlọrun lọna gbo gbo, larin ile, ọrẹ ati ẹbi, bi o ba si ri ọna titun ti enia le fi ba wọọ maşe jafara.

ARIES (Mar 21—April 20) Maşe da işẹ rẹ ru masi şe jeki o pa o laiya o san ki o kuku din işẹ ti o nşe lọjọ ku ki arẹ ma ba mu ọ ki gbogbo işẹ rẹ ma ba daru

TAURUS (April 21—May 20) Arẹ fẹ mu ọ şugbon o yẹ ki o le gba ara rẹ silẹ o si ye ki o lo fi ara lelẹ tabi ki o sun.

GEMINI (May 21—June 21) Ojọ oni dara, ero ọkan rẹ si dara pẹlu, şugbon iuawo airotẹlẹ yio de si ọ, akoko aşalẹ yio si miringindin fun o iwo yio si gbadun awon alojo ti o wa ki ọ.

CANCER (June 22—July 22) Işẹ ti o fẹ şe loni yio po arẹ ni yio si pẹkun rẹ fun ọ. da awon işẹ ti o ku duro ki o si lọ fi ara lelẹ:

LEO (July 23—Aug 22) Iwọ lo ni ọyaya si enia, nitori ki o fi ara mo ohunkohun ti o ba de, şugbọn ki o ma şe ọmọya.

VIRGO (Aug 23—Sept 23) Igbehin ohun ti o da silẹ yio dara, iwọ yio si tun ri nkan iyanu lati ọdọ awọn ọrẹ ati ẹbi wa

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Gba ara rẹ kuro lọwọ amodi ti o nşe ọ, sibẹ ire mbẹ fun ọ loni

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Boya o le şe akiyesi wipe ọrọ ara rẹ ko lọ deede mọ bi o ti ni lati lọ, ki o şe suru ki o si şe ohun ti o ye ọ pe, ko ni pẹ ka kuro.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ki o pupe lọwọ ero rẹ ti o pe iwọ yio ri ire, aşiri rẹ si bo gbogbo ohun ti iwọ ko ti ri aye lati yanju ni o ki o mojuto

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Ọrọ awọn ẹbi rẹ yio ni tẹlọrun, şugbọn sibẹ arẹ si mbẹ lara rẹ, o yẹ ki o ọ fi ara lelẹ, ki o si din işẹ rẹ oni ku ki o ba ri aye simi


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYAMIREN TONIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọ Imamọnu, tiluni ti gbogbo a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daji fun Agbara ati Ajẹbidan şẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinringbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi işẹ şişe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn şaa ara rẹ gbogbo ki şefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kulẹ daradara wọn işẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di titun pafapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o gbunjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni agba yio sao pẹlu ioq m udeu brode o iyẹn da baş



Waterloo Medicine Stores
8 Palm Church Street Lagos

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos
Phone 22878 Nigeria (Ọja Ita Faji)
LAGOS



IWE KOŞEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da şe AYẸWO fun ara rẹ

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)

# Awon Tun Dana Oselu Tun Sun Kan

AKURE:— Omo egbe oselu kan ti awon janduku kan ti lo jo oko koko ti ogbin, ile ti o ko ti gbogbo dukia re si sofo sinu ile re ti nwon jo ni o t salo si ilu Ibadan, ti o si ngbe ibe lati osu meji s hin; Ogbeni Julius Akindero wi pe, ija ti o ti ruk nilu re l ' a r ni o ti npada bo wa si ilu re Idanre.

Ni o ba ko pada wa si ilu Akure lati gbe ni e f u n igba d e ki o to pada si ilu re ni Idanre o ti ngbe ori aja fun opol po igb , ni- gb ti o se o tun ngbe i n u ile died e o tun nyoju sira, nigbati o wa kalara ni o ba tun nsire ni sa u ile t o ti nse stipo ni Akure.

Eniti oro na se oju re so fu o tirohin a pe, Ogbe ni Jul us Akindero nba ore kan soro niwaju ile ti o ng e ni okan n nu awon ti o ti nwa ba ri ni nwon ba da ep petiro si lara, O r e re ti o n s ro ti i o h u n buruku ti o sele loju re ni o ba fi ese fe e.

Nwon ti e b e ogbeni Julius kirde o lo si ile oogun so f n wa pe e m i kan soso ni o ku lenu re bayi.

Iroh lati ilu Ekiti tun s pe pe, ogbak igi o m o egbe Demo kan t u n ti fi egbe Demo sile ninu ro ti Oloye S A Daramola so fun onirohin wa pe, nit ri edeaiyede ti o wa ninu ilu na on fi egbe Demo s i l e patapata ati pe on fi ise lu sile titi, d on y i o fi fi aiye sile.

Olo e Daramola wa gba- dura pe ki alafia ki o tete pada si ilu Ekiti.

# Congreves Female Remedy

(FUN OBINRI )

Ojulowo egbogi fun gbogbo awon Obinrin boba ba ni iyonu tabi amodi, Inu rirun nigbakugba tabi ni eko kan ehin didun, Ibadi-wiwo tabi si an eyedudu ara tabi a koto eje I ra nu gbigbona nigbakugbe.

Igba aiya riru omu riro, didun ara aiin wa ni o ma nfa oyi eju Ilaogun ara ese ara sisan, ef ri tabi pelu inu ati otutu Egbogi yi dara pupo julo fun itoju gbogbo Obinrin gegebi Aio fun ilera ati orisi isi amodi mirun ba ma nyo won lenu nigbakugba pelu.

(OLOMI GINLA NI)
BERE EGBOGI TI WON NPE NI:—
**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba a l i ki awo Orisiris rubir bi egoogi ti won ko wa ni-i-iyi to de awon agbalagba alaye atijo mo daju wipe kosi ohun ti o le fi we e bogi yi bi otutu, Iko, Iba, Orere, Lukuluku, Onigb meji tabi iperi nyo enia lenu yala Om de tabi Ag agba ni y o se iwosan re bi d ni g i bi o t a ti ta d e si u emi ti o lo voro k o si gbemi bere eg ogi ti o daju fun itoju eti riro tabi didun a tu Akokoro e gbo ti o ma nfo apo ile ito tabi se iwosan d nu ap le ito egbogi oja ddun tabi ti ona ofuu di dun ati orisirisi omir n pe u wo mte ni sohu awo :

Waterloo Medicine Stores
8 Palm Church Street Lagos

# Awon Agbagba Soriko-do Lati Wa Irepo Larin Yoruba

Abagba Yoruba sori kodo awon woye lo sun nwon wipe agbalagba ki wa ni ja, ki ri omo titu wo, nito r na bi nwon ko ba tete dide si rogbodiyan t be si e la- rin awon Yoruba yi o le se be k o di ogun Dahomi, ni torina o mbo, o mbo, awon e ia nde sile fun Awon egb gba lokuorin ati lobinrin dide lati wa ipari ija na.

Nwon ti lo ri Aihaji Adegbenro olgboro Idadan nwon si tun lo ri Oloye Iyawo Awolowo oro na si fi ara han bi ey ti o loju, sugbon ibiti koko oro na wa ni odo Oloye Awolowo nitoripe aisi le re lo fa gbogbo ijogbon yi wa ni tori idi eyi awon agbagba nwoyi dide lati lo fi oju ganni Oloye na nibiti ogbe wa ni Kalaba awonyi i oruko awon agbagba to lo s be Bishop Odutola awon Oba ile Yoruba awon O o- ye ilu ati awon Ijimi ilu

Nigbati awon enia na pada de si Ikeja Oliwe wa kan bere pe bawo ni ohun ti ri? Bishop Odutola da- hun pe oro na si nle loju nitoripe awon ti lo fi oju kan Ol ye Awolowo o si ti fu i awon ni es to d u pe gbogbo ero okan ou ni pe ki irepo wa lari i iran Yo ruba eyi si ni ohuntio mbe lokan on nigba gbogbo.

Die ninu awon Ijoye ti o tun ba won lo si Kalaba ni wonyi Oloye Adeyemo Alufi Falode, A h ji El as Oloye Abiola Akerele. Asi tun gbo pe awon egbe Ob nri Olo a Eko to yan awon asoju lo sodo Oloye Awolowo nipa oro yi nan na nwon ti ri Alhaji Ade— gbe ro nwon si ti ba Iya wo Awolowo s ro papo itelorun ni gbogbo oro ti nwon gbo

# Ha Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN META NI

Three Elephant Brand mosquito coils d ra pupo An O dara iu gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku l i

O npa yanmuyanmu ninu ile n kiakia orun re sl da ra pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lo Bakanna ni o si tu yara pa ay n ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Bran coils tire loni, ki o si d i w, iwo yio ri bi o ti se pa gbogbo yanmuyanmu inu ile re ti iwo ati awo omo re y o si sun d radara

Ko o ti d jo pe ogun yanmuyanmu o' ri erin m etay nw n mu un o

Th ee Elephant mosquito Brand coils yi wa n sobu citaja kakiri Orile ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,599 FRIDAY DECEMBER 31, 1965 (2D)


## Nwon Dana Sun Moto Koko Ni Mushin

MUSHIN.- Gbogbo enia to wa ni Oja Mushin lo beresi sa asala fun emi won ti Olorun ngbo nigbati awon enia kan da moto akeru nla kan ti o ko apo koko eyiti nwon ti gbe le ori iwon ti nwon si ti won dana ti awon enia na sa losi awon apo koko na eyiti o je pe gbogbo moto ati awon apo koko na lo si jona patapata eyiti o fi je pe gbogbo awon enia to wa nitosi lo si nsa asala fun emi won nigbati isele na sele.

Irohin lati owo awon Olopa ti ilu Mushin fi ye wa pe nwon ko mo iru awon enia ti nwon dana sun moto pelu awon apo koko to wa ninu moto na. Sugbon awon olopa na tun se alaye pe awon enia ti o dana sun moto pelu awon apo koko na si je awon janduku omo egbe oselu.

Nigbati Oniwe irohin wa lo fi oro wa oga agba awon Olopa ti ilu Mushin lenu wo lori isele to sele na ni o se alaye fun Oniwe irohin wa pe otito ni moto jona ati pe Olopa na taku lati soro lori awon apo koko to jona ninu moto akeru nla ti awon enia na dana sun.

Awon Olopa ko ti ri enikankan mu lori isele to sele si moto ati awon apo koko na.

# OMO EGBE UPGA MEFA JARE EJO

OSHOGBO:- Ni ojo Isegun ti ise ojo kejidinlogbon osu yi ni Adajo ile ejo kekere ti ilu Oshogbo ti pase pe ki omo egbe Afenifere ni Ile Igbimo Asofin apapo Ijoba Naijiria ati Olori egbe na ni ilu Ikire Ogbeni Ademola Olaniran ati awon omo egbe UPGA marun ma lo ni ayo ati alafia lori esun pe awon enia na lo ba nkan je, ati pe awon enia na tun ko awon ose lowo ni igboro eyiti o lodi si ofin pelu pe awon enia na fe ba alafia ilu je eyiti awon olopa fi kan awon omo egbe UPGA mefa na.

Ninu oro olopa to ba awon egbe UPCA marun se ejo ni o ti se alaye pe ninu osu kini odun yi ni Ogbeni Olaniran ati awon omo egbe UPGA marun kan lo ba moto awon egbe oselu kan je ati pe awon enia na tun ba awon dukia awon enia miran je ni ilu na.

Nigbati Adajo kotu na gbe ejo na dide ni opin ose to koja lo ni Olopa to ba awon omo egbe UPGA na se ejo se alaye fun ile ejo na pe on ko ri awon eleri ti yio jeri ni kotu na ati pe on fe ki nwon sun gbigbo ejo na siwaju titi di asiko miran eyiti awon eleri yio fi le wa ni ile ejo.

Ninu oro Adajo kotu na Ogbeni John Ayinde ni o ti se alaye pe on yio tu ejo na ka titi di asiko ti olopa to ba awon omo egbe na se ejo yio fi ri aye lati pe awon eleri re.

Nigbati Adajo so eyi ni Olopa to ba awon omo egbe UPGA na se ejo ko mo ohunti on le fi fun Adajo ni esi mo.

Ninu idajo re, Ogbeni John Ayinde se alaye pe ko si esun kankan to fi idi mule ti nwon se fi mu awon enia na, ni o ba tun se alaye pe; on da awon enia na sile layo ati alafia ati pe nwon ko ni ejo kankan lati je niwaju on, Bi Adajo ti se idajo na ni Ariwo Awo! Awo !! Awo !!! si gba kotu kan,


**Asalam Alaikum Jammah !**

**Nafila Oru Osu Ramadan.**

Lati Owo ALUFA AKEWULA

ORU OJO KESAN 31/12/65 : Irun mejo, Salamo merin lori iduro Irun kookan, eo ke:-Fatiha kan; Tabatiada meta. Kulihau-Allahu meta

KA IROHIN—IMOLE FUN NAFILA TI OLA


### LATI OJU EWE KINI

Akintola ba ni ife awon omo Yoruba lokan ni, ki ba ti sare fi aye ti o wa ni oni yi sile siwaju asiko yi, nitoripe lati ojo ti nwon ti dibo na tan ni rudurudu bere si ma a sele yika gbogbo Ipinle Iwo Orun.

"Lati igbati gbogbo ohunkan ti o nsele wonyi na si ti beresi maa sele, ni awon ti nwon je ojulowo omo Yoruba ti nlo na Oloye Akintola ni koko ati ni gbangba ti nwon si nsipe fun un wipe, 'gbogbo ohunti o de le yi, ko le kase koro nile a fi bi Oloye Akintola ba kuro ni aye ti o wa nisisiyi.

Oloye Ogunsanya wa bere bayi pe, "Bawo ni Oloye Akintola ti se nsoro ife tabi, iru fe wo ni Oloye Akintola nso nigbati o je wipe, Olori ti gbogbo awon omo Yoruba nfe wa ninu ogba ewon nisisiyi, ti o si wa je wipe enia nwon ko fe, lo tapinpa si won lorun, ti o ko ti ko o?

"Ki ise ohunti o dara fun Oloye Akintola lati ma so oro ife larin awon omo egbe UPGA ati omo egbe Demo ni asiko yi gegebi Oloye Akintola ti se nso nisisiyi,

Oloye Adeniran Ogunsanya tun so siwaju ninu oro re wipe, "Ohunti awa omo Yoruba nfe nisisiyi ni wipe ki a ni ironupiwada, ero tuntun si ara wa, tabi larin gbogbo enia, nitoripe gbogbo ohunti, o nsele yika gbogbo Ipinle Iwo Orun loni, ko si enia iru re dun mo rara,

"Bi a ba si mo wipe won ohunti o nsele na ko dara ka, o fe, wipe ki nwon na da ina sun ile ki nwon ma yinbon pa enia ati ki nwon ma dana sun moto larin ode gbangba, ki ise ohunti o dara, o ye ki leo se atunse re ki iwa bayi si le dawo duro nitoripe a ni ife awon enia ti a nse Olori fun.

Oloye Ogunsanya tun so fun Oniwe Irohin wa wipe, gbogbo awon omo egbe Demo, bi awon Oloye Ayo Rosiji, Remi Fani Kayode, Oloye A M A Akinloye, ati Bibitanyi Olowofoyeku, ni awon omo Yoruba ni ife won lokan daada, sugbon ohunti o jeki nwon korira won awo enia na loni ni wipe, nwon wa ninu egbe ti awon enia na ko fe, egbe ti gbogbo awon omo ile Yoruba nilo ati loko ka si egbe "ODALE"

Oloye Ogunsanya tun so wipe, "Bi Oloye Akintola ba ni ife awon omo Yoruba gegebi o ti se nfe, ki ise wipe enu ni yio ma a fi so wipe, on ni ife awon omo Yoruba, kakiri, bi o ba tile nfi enu so kaakiri, gbogbo awon enia ti on nso fun wipe on feran won ni awon paapa yio mo ti nwon yio si tun ma ri ninu ihuwasi Oloye Akintola yika Ipinle Iwo Orun ati yika gbogbo Orile ede ile Naijiria pelu

Awon omo Yoruba na ni nwon yio ma fi enu ara won so kakiri wipe, Oloye Akintola feran awon nipa ise ti o ba nse fun won yala ni Ipinle taci ni Fedira, ki ise wipe on ni yio maa fi enu arare so wipe, on feran awon omo Yoruba

Ni ipari oro re, Oloye Ogunsayan so wipe, bi o ba je wipe nitooto ni oloye Akintola ba feran awon Yoruba gegebi o ti o ti se nwi kaakiri, nigbati awon Yoruba si so wipe awon ko fe ki o wa ni aye re mo o ye ki o si fi aye re na sile nitori ife ti o ni si won


Printed & Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 31/12/65